Anabi – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ṣe aluwala ni ẹyọkọọkan

Lati ọdọ ọmọ Abbās – ki Ọlọhun yọnu si awọn mejeeji – o sọ pe: Anabi – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ṣe aluwala ni ẹyọkọọkan.

[O ni alaafia] [Bukhaariy gba a wa]

Anabi – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – jẹ ẹni ti o ṣe pe ni awọn igba miran ti o ba ṣe aluwala yio fọ oríkèé kọọkan ninu awọn oríkèé ara rẹ ni ẹẹkan, ti yio fọ oju – ninu rẹ ni yiyọ ẹnu ati fifin imu -, ati ọwọ mejeeji ati ẹsẹ mejeeji ni ẹẹkan, ati pe eleyii ni odiwọn ti o jẹ dandan.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/65081